# IWE SI OLOTU IROHIN YORUBA

## Itumo Alo-Bibeli Prophet Peter A. Oyinloye

Awọn ti o tumọ alọ-Bibeli ti Prophet A. Oyinloye pa sinu Iwe Irohin Yoruba ti 31/8/53 ni a to orukọ wọn si isalẹ yi ati bi nwọn ti tumọ alọ-Bibeli na si.

1. Sadraki, Mesaki ati Abednego, Dan 3: 1.
2. Nebukadnessari. Dan 3: 4 - 5
3. Ọlọrun, Dan 3: 17
4. Adura gbigba si Ọlọrun
5. Awọn Olori ogun ti o gbe awọn mẹtẹta na sọ sinu ina ileru. Dan 3:22.
6. Ina Ileru. Dan 3: 20 - 22.
7. Ọlọrun ti O ran ọmọ Rẹ lati gba wọn la.

Awọn ti o fi idahun itumọ alọ Bibeli oke yi ewọ bakanna ni:-

Ọgbẹni Samuel Idowu Ajibinrere Eko.
2. Ọgbẹni Samuel A. Onila - Faaji, Accra, Gold Coast
3. Ọgbẹni Awoko Jesu, Ibadan.
4. „ E. A. Fabunmi, Ile-Gbọrọ Idọgọ.
5. „ S. A. Ogun (Fija - Fọlọrunja) Kemta Abẹokuta.
6. „ A. B. Idowu Aiyeẹru, Oke - Bọla Ibadan.
7. „ M. A. Kokere - Ẹkun, Iwo
8. „ Sammy Ade Ample, Kumasi, G. C.
9. „ Eeran Ọlagunju - Mọkọla St. Ibadan.
10. „ Eman Ọla Ilori, Ibadan.
11 „ Mofọlọrunṣọ Ọlanipẹkun, Ibadan.
12 „ Abel Ṣekoni, Shaki.
13 „ Jacob Amusan, Ẹdunabọn via Ifẹ.
14 „ S. A. Shoetan, Sabongari Ilọrin
15 „ I. L. Majọlagbe, Asankarangwa G. C.
16 „ Solomon Ọla Akinrẹmi, Abalabi Station.
17 „ J. A. Lagunju, Kumasi G. C.
18 „ S. Laniyan, Potiskum.
19 „ E. O. Asanlaiye. Kumasi G. C.
20 „ James A. O. Ọlaniran, G. C.
21 S. Adepọju Ọlatundun, Box 42, Ikirun.
22 G. Bọlarinwa. Ibadan.

2 Awọn ti orukọ wọn wa ni isalẹ yi ni idahun wọn yatọ si ti awọn toke yi, ṣugbọn lati inu Iwe Woli Daniel ori kẹta na ni nwọn ti ndahun rẹ ati pe itan kanna ni nwọn juwe nipa Sadraki, Meṣaki ati Abednego. Ibiti idahun wọn ti yatọ ni a o juwe.

23 I. O. Adekẹye, Ẹsiẹ Iṣba Ọffa. Idahun ti o fun ibere kẹfa ni "Ọlọrun".

24 E. O. Awo I. Ibadan, Idahun rẹ si ibere kẹfa ni Jesu.

25 Timothy O. Ladanu, Jones Ogbomọsho, Idahun ti o fun ibere kẹrin ni "sinsin ere orisa ati titẹriba fun ere wura na.

26 Engineer Rufus Toromide Ibadan, Idahun ti o fun ibere kẹfa ni "Awọn iranṣẹ Ọlọrun.

27 S. Ẹmilọla Ayọ Okusanya, Ibadan, Idahun ti o fun ibere kẹta ni "Ilu Babeli ati awọn ngberiko rẹ," Ikẹfa ni "Nebukadnasari" ati ikeje ni "Angeli ti o wa ṣe ẹkẹrin wọn ninu ina."

28 S. Oye Akande, Aipata Iwo. Idahun ti o fun ikẹta ni "Nebukadnassari" Ikẹrin "iwiwasu ọrọ Ọlọrun kakiri ilu na" Ikarun ni awọn igbimọ ilu Nebukadnassari, Ikefa ni "Eṣu."

29 Ọgbẹni J. A. Amsie. Dunkwa G. C. Idahun ti o fun ibere kẹta ni "Adura awọn ọkunrin yi."

30 Joseph Elefọla (ọmọ Ilu Ọwọ) ṣugbọn nisisiyi o wa ni Orthopaedic Hospital Igbobi, fun aisan (ki Oluwa fun un ni ilera o. Amin.) Idahun ti o fun ibere kẹta ni awọn Angeli.

31 M. S. Adebayọ (Ọlọla Daodu) Owode-Abẹokuta idahun ti o fun ibere keji ni pe Ere wura ti Nebukadnessari gbe kalẹ.

32 Ezekiel Alamu. Aṣa Iṣba Iwo. Idahun ti o fun ibere kẹrin ni:- Awọn ọkunrin mẹta na ni Ọba fi jẹ Olori ọran igberiko Babeli lati ma a wa ooje jẹ.

33 J. A. Adu. Epiomi Akoko, Idahun ti o fun ibere kẹta ni:- Awọn Ijoye Nebukadnessari ati idahun fun ibere kẹrin ni:- Ilu Ọba na ati gbigbe awọn mẹtẹta ni ilu na.

34 J. A. Ogungbile. Idahun ti o fun ibere kẹta ni awọn Igbimọ Ọba na.

A ko le sọ bi awọn ti o fi Wo oju ewe kẹrin


## Irora Ehin Didun

NIHIN NI ỌNA IDẸRA !

Iwọ ha mọ pe ohun ti o nṣaba fa irora ẹhin didun ni ki awọn eree (Kidneys) ma si laye to dara? Ti nwọn ba mbẹ daradara nwọn a ma a sẹ awọn idọti kuro ninu ara. Ti nwọn mba fatikọ lati siṣẹ, awọn idọti wọnyi a ma a wọjọ pọ si oju kan na, apapọ idọti wọnyi ni o si ng mu ẹhin didun wa.

Ohun pataki ti o mu wa ṣe De Witt's Pills ni lati le jẹki awọn eree (Kidneys) ti nwọn nfa ipọnju iṣẹ wọn le ma a siṣẹ daradara. Egbogi yi ni agbara atata lori awọn eree wọnyi, yio tun wọn ṣe yio si jẹki nwọn ma a siṣẹ dede. Didun ẹhin na si kuro.

O kọja adọta ọdun ti De Witt's Pills ti ngmu idẹra ba awọn ọpọlọpọ enia ti ẹhin ndun, a si ti ri aimọye iwe ọpẹ gba lọdọ iru awọn enia bayi kakiri aiye. Tete mura lọ si ile ọja egbogi, ti o ba ri egbogi yi ki o ra a loni yi gan an.



IJẸRI SI WA !

Egbogi De Witt's Pills jẹ eyiti a se pelu imọtoto ti gbogbo enia ti a fi ye e si jẹ pipe

DE WITT'S PILLS

for Kidney and Bladder Troubles


## Iyawo Dun L'osingin Ọko Tun Mi Gbe

OGBOMỌSHO — Iṣawo igbeyawo na busiya o ie pongo ni Agboile Afẹjẹwẹ Oke Agbẹnhin ni ọjọ Ibọ ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni ọjọ ti Ọgbẹni E. A. Ogunlade gbe Omidan Oyebinpe ni iyawo ni Ile Isin Ọlọrun Oniṣẹbomi, "Emmanuel Baptist Church" Isalẹ Affọn. Alufa Ijọ na ni o ṣe alakoso isin igbeyawo na.

Baba Iyawo na ti o ti Jos wa na owo pupọ ni ọjọ na, bẹni inawo ti Baba ọkọ - iyawo na Ọgbẹni Ogunlade ko si i sọ, bẹna ni Ọgbẹni J. A. Ogunlade, ẹgbọn ọkọ - Iyawo ti o wa lati Ẹko nawo pupọ nibi igbeyawo yi.

Die ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeye ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Samuel Ajala Carpenter, D. Ọpajinka, J. Alapo, J. Oyelade, J. A. Akande Repairer, J. Agbọọla ati Ọdẹjinmi.

Ọkọ Iyawo na ati Iyawo rẹ ni ti npalẹmọ a ti pada si Oke Okun (Kumasi Gold Coast).

Ki Oluwa fi adun sinu igbeyawo na o.


# Tete wo Iko Re San




Bi ikọ ba nfin ọ ni ọna-ọfun ti ko si jẹki o sun l'alẹ, mu iwọn iba Veno's diẹ ki o to sun.

Ti o ba di ẹ ni aiya ti o si fun ẹ ni inira mu Veno's, lẹsẹkẹsẹ ni wa ti ri irọrun ati itura.

Bi o ba ti d'ọgbẹ si ẹ ni ọna ọfun, gbogbo rẹ ni Veno's yio mu kuro.

Fi Veno's si arọwọto rẹ fun lilo awọn ọmọ ati aya rẹ, iba ṣe ọmọde tabi agbalagba. Tete lọ ra igo kan loni.

Sa Mu

VENO'S

LIGHTNING

COUGH MIXTURE

